GO PLACES
IN A
HILLMAN
FROM
ARAB BROS
MOTORS LTD.

ỊROHIN ỊMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye Oro**

Jẹ Ọlọgbọn bi ejo jẹ oniwa tutu bi adaba, kanju lati gbọrọ, ṣugbọn lọra lati dahun. Ki a ku ni ọlẹ-mẹsọ ki o yẹ ni, o sanju ki a di agbalagba ki a mọ ni adiọ raza lọ.

VOL. V No. 200 MONDAY JUNE 12 — JUNE 18 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Omo odun mefa kan jeri tako Iya re wonle, ninu ejo apania

IBADAN:- ỌMỌ ỌDUN MẸFA KAN TI O NJẸ MỌJIṢOLA ADEGBILE LO JẸRI NIWAJU ADAJỌ AGBA NILU IBADAN, NINU KOTU ỌDARAN IGBORO ILU IBADAN WIPE, IYA ON TI O NJẸ FELICIA OLUFUNKẸ LO MU ẸGBỌN ON KAN TI O NJẸ ADEỌLA LỌ SILE IBITI NWỌN NKO ONJẸ SI, O SI GBE SODA (MAJELE) FUN MU.

OHUN TO JẸKI O SE BẸ NI WIPE, ADEỌLA NI INU NRUN ON NI AKOKO NA, TOBẸ TI O FI NSỌKUN. MỌJISỌLA SỌRỌ YI LATI TAKO IYA RẸ NIGBATI ẸJỌ IYA NE BẸRẸ, NINU EYITI NWỌN FI FELICIA IYA RẸ SUN ẸSUN APANIA.

Lẹṣẹ kanna ni Adajọ bere lọwọ Mọjisọla ọmọ ti o njẹri tọka Iya rẹ wipe, bawo ni iwọ tiṣe mọ wipe Soda lo gbe fun Adeọla mu, nigbati iwọ ko si nibẹ? Iya ẹgbọn mi lo sọ fun mi bẹ, emi ko fi oju mi ri nigbati Iya mi fi npo Soda na.

Orogun Felicia ti iṣe Iyale Baba to bi Adeọla ti o ṣalaisi na lo ti kọkọ rojọ tako Felicia, o wipe lọjọ buruku on fun Adeọla ni onjẹ ki o to jade lọ, ko si pẹ lẹhin na lo pada wa sile ti o nbi e e b i ọṣẹ ati ẹjẹ, on bere nisoju Ọdaran yi wipe, kini ohun ti o ṣe e, Ọmọ na si tọ ika si Felicia Ọdaran yi pe on lo fun on ni nkan mu.

Adajọ bere wipe iwọ to ọdun melo nile ọkọ o dahun wipe on di ọdun merindinlogun nile ọkọ Ṣugbọn Ọlọrun koiti jẹki on bimọ fun ọkọ wọn, ko si si ede koyede kan larin on si Ọkọ wọn ati Ọdaran yi pẹlu.

Dọkita Oruwariye ti yẹ oku Adeọla wo sọ pe laisi tabi tabi soda lo pa ọmọ na, nṣe lo si jẹ soda bi onjẹ. Ẹjọ na si mbẹ ninu kotu nwọn koiti pari rẹ, ẹ o ma gbọ bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si.

## Ijoba Ibile Mushin se ofin pe awon Ewe ko gbodo kiri oja mo ni Mushin

Ijọba Ibilẹ Mushin ṣe ofin wipe awọn Ọmọde ti ko ba to ọdun mẹtadilogun ko gbọdọ kiri ọja Tita mọ ni Mushin o si tun lodi si ofin bi ẹnikan ba pa Atibaba, tabi tẹ tabili lati ta ọja tabi onjẹ ni itagbangba yato si kọlọfin ni abẹ aṣẹ Ijọba Ibilẹ Mushin

Enikẹni ti Ijọba ba lọwọ si lati ta ọja beya o fẹ kọ Atibaba tabi tabili fun tita ọja ati onjẹ ni ita gbangba yio gba iwe aṣẹ itaja ni ibi iṣẹ Ijọba Ibilẹ Mushin, ṣile kan ni owo iwe na, iwe itaja na kiṣe eyiti a gbọdọ fun ẹlomiran lo, ṣugbọn awọn ti o ba fẹ ta Pako (Timber) Ayun (Sawn) ati nkan ọṣọ ile (Furniture) ni lati san ṣile marun fun iwe aṣẹ gbigbe. Iwe aṣẹ na, a ni lati lo nigbogbo agbegbe Mushin, ọjọ si ni ao ma pari rẹ.



## Awon Oniwe Irohin ile Naijiria ni ile Jamani

Awọn enia mẹta ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Oniwe Irohin ilẹ Naijiria ti awọn da kan lọ ṣe abẹwo ilẹ Jamani nilu Oyinbo ninu oṣu to kọja lọ. (West Germany and Republic of Germany

Ninu aworan ekeyi, Daddy ti o duro lọwọ ọtun ni Aṣoju ilẹ Naijiria (Nigeria Consulate) ti o mbẹ ninu ile Jamani lo mba awọn Oniwe Irohin na sọrọ pataki.

Oruko awọn Oniwe Irohin na ni, lati owo osi, Ọgbẹni Umana, Ọgbẹni Yusufu, ati Ọgbẹni Oloyede.

# Kere o, Kere o, Odo ma gbe Omowe lo o,

Lati Qwọ:- Eni Owọ ỌMỌ ARIDẸGBAJU (ORO)

O BẸRE LATI OṢU TO KỌJA

Mo fẹ bere lọwọ ẹyin Ọmọ Iyami ti nse Ilọrin, Ọffa Igbomina, Ekiti ati Kabba papa pẹlu, kini ọrẹ ti awọn ẹgbẹ Onigbale wọnyi Ṣesi ilu Onikaluku yin Kiẹto maje ara yin ni Iya pe, Ọrun Isu ni kanrinkan ku si? Tabi awọn baba yin to Sọnu si Ibadan lọfẹ walọ nibi? Ẹyin oselu ilẹ Ilọrin Igbomina' Ọffa, Ekiti, KABBA, Tiẹ jẹ ẹgbẹ Onigbale ni ilẹ Ariwa ẹ pada lẹhin wọn ẹyago fun OPẸ ẹma se ṣe ẹgbẹ OKUNKUN. Nitori enia meji Kogbọdọ padanu irọ rara, ti ẹniti iwọ npa fun ko ba mọ pe irọ ni iwọ npa, iwọ papa na yio ti mọ pe iwọ npa irọ.

Ọrọ nipa Division kose Division, otitọ otito mẹta ti mọ ti ngbọ ti Ọgbẹni M. A. Ọdẹkunle ti se akọwe kekere fun ẹgbẹ Igbomina parapọ eyi ti o wadi ẹgbẹ Onigbalẹ nisinsin yi. Nigbati mo ro ọrọ Ọgbẹni M. A. O. yi wo ti ti o wa ja si pe ọmọ ẹniti Ikabi Ika na ni yio jọ. Ika kojẹ ki paramọlẹ o dagba, ẹyin ọmọ ilẹ Igbomina Ọffa, ati Ekiti tani ko mọpe o daju pupọ ni awọn ọdẹ ti osẹsẹ wa fi ẹnu ara rẹ sọpe Ọdẹkunle, ni di eyi ati mọ pe iwọ ko bikita awọn enia lọkan rara bẹ na ni awọn Ọdẹ ṣe, nitoripe ọgbẹni M. A. Ọdẹkunle yi ti ntẹ mi ni ori mọlẹ emi ko sọrọ, ti o ba wa tẹ mi ni iru mọlẹ ni sinsin yi, emi yio ge jẹ ti o ba si bere ha iwọ yio gbọ esi ho. Mo wa mu ibere wa si ọdọ iwọ Ọdẹkunle yi pe, boya awọn ti wọn jẹ oselu si wa ju rẹ ko mọ wipe Division to dara ju ni, ki wọn to sọ wipe a o pada lọ si iwọ Orun, lati bi ọdun mẹwa (10years) ti wọn ti nlo wa ni ilo kulo bọ wa Nigbati ẹ wa ri wipe Odo-Ọya Ado Osa, Odo oyin, Odo- Ipo, Odo-Ọṣun Odo-oyi Odo Awẹrẹ, ati Odo-Agban to gba yin lọ tan ẹyin wa nke igbe pe ki ẹgbẹ Olomi N.P.C. wa gba yin silẹ, ẹyin ko mọ wipe awọn ẹgbẹ Olomi N.P.C. loni awọn odo ti ngbe yin lo ni, kini ṣe ti ẹyin ko fi pe awọn oga yin ti wọn npolowo ibo loke ọrun, ti wọn fi ọwọ ara wọn da ibo wọn sinu omi ni December 1959. ti wọn si fi ọwọ arawon mu Igbalẹ gba arawọn danu ni ọjọ kẹrin oṣu may 1961 (4. 5. 61. ) Ni ilẹ ariwa. Eyi to tilẹ wadun mi ju nipe ki enia mamọ ọna kio madiji gbe Oluwa rẹ yio sọ ara rẹ nu ni. Ha Ọgbẹni Ọdẹkunle Emi ọmọ Aridẹgbaju fẹ fi yin mọ ọna iwọ wa nsọ wipe iwọ rope, Baba emi ọmọ Aridẹgbaju mọ nfi idẹ gba awọn ara Ijo hun ni oju ni, anu se mi pe ọmọde londamu rẹ ọrọ ọmọde ni mo ka kun, atipe emi ti ko ba sọrọ ṣugbọn mo ti ju awọn ọmọ ilu rẹ, bi o ti lewu ko le mọ ilu ṣa ni ilu rẹ nṣe. Ọmọ ọla kisọ isọkusọ rara. Mo wa fi eyi kilọ fun ọ dada pe eyi yi koto eyi ti iwọ le ma bu mi nitori iwọ nsọrọ, emi papa na nsọrọ o sida ẹ loju pe emi ati iwọ kogbọn to awọn ti nka iwe Irohin Imọlẹ nitori idi eyi ọgbẹni Ọdẹkunlẹ jẹki kẹkẹ pamọ atioro lẹnu o, ọrọ irin ajo mi fun odidi osu mẹta nilẹ Igbomina, ati orukọ ilu ti mo de ẹnyin yio ma rika ninu Irohin Imọlẹ laipọ yi.

Ẹnyin o nkawe mi gbogbo eti nyin koni di, oju nyin ko ni fọ, ẹ jọwọ ẹ mase agbara lati ma ra Iwe Irohin Imọlẹ ni ọjọ keji ọsẹ ti ṣe Monday. Iwọ oiwe 'Rohin mi na ọkọ ọba ko ni sa nyin lọsẹ o, emi ọmọ Aridẹgbaju quro nihin Emi ọmọ nmọjọ nmakin oro, ọmọ ewe dunmoye emi ọmọ Ajigbọtolọ, ọmọ ibinu ko da nkankan suru baba iwa, ọmọ Asorodi Ilọrin, a sọ oke-ọla di dugburu agba tohun wa ibajẹ ti nlọ si oke-ọla bi ẹni nlọ si Sokoto, emi ọmọ Aridegbaju ọkọ parapọ.

Olotu mo dupẹ. Odigba.

---

## ISE KI PANI, AYO NI PA ENIA

Lati Qwọ:- SIMEON ADEGOKE FATOKI

O BẸRẸ LATI OṢU TO KỌJA

Ṣugbọn Ọlọrun da wọn si o si nwo wọn bẹya wọn le ronu piwada ki a si dari-ji wọn, ṣugbọn ni igbẹhin ọjọ aiye wọn nigbati Ọlọrun ri pe wọn ko ronu piwada, ni ọjọ kan wọn lọ si ilu kan bi ọgbọn ibusọ si ibi ti wọn ngbe, tọkọ taya wọn. Nigbati wọn de ibẹ wọn mu ọti yo wọn nse bi o ti wu wọn, nigbati wọn si nbọ ni ọna, ọkọ ayọkẹlẹ wọn se ijamba awọn mejeji si ku ni ẹsẹkẹsẹ. Iru niyi ti a fi jẹ ki wọn wa nibi ati lati jẹ apẹrẹ fun awọn ti o nba ori wọn nibi yi, ti wọn ba ti ka akọlẹ yi ki wọn si ronu piwada inu ọna buruku wọn.

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

For all your Printing Requirements

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.

## Alufa ti o nse atunse bi nwon ba se asise



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni ti ọkan n in u awọn Alufa enia Ọlọrun ti o nyẹ awọn ọrọ inu Bibeli na wo bo ya asise le wa nibẹ ninu ilẹ itẹwe ti Oxford. On nikan ni yio ṣe ofin toto adọta ọkẹ na, iṣẹ rẹ ti o si gba owo le lori nuni.

---

Ẹ MA KA IWE IROHIN IMỌLẸ NIGBOGBO IGBA KI ẸSIN MA POLOWO ỌJA YIN SINU RẸ.

## Nigerian Ports Authority

### Vacancy - Dockyard Engineers.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Dockyard Engineers in the Authority's Dockyards.

QUALIFICATION:

Candidates should be in possession of the Ministry of Transport 1st Class Certificate in either Steam or Motor; a combined Certificate would be an advantage.
Holders of equivalent qualifications in Marine Engineering will be considered. Preference will be given to candidates who in addition to the above, have experience of Dockyards, Slipways and/or Floating Docks and other land based Marine Engineering experience.

DUTIES:

The duties of the post will include Marine Engineering repairs, overhauls and maintenance of vessels in the Authority's Dockyards.

SALARY:

Scale 4 (b), £1 350 x 56 - £1 742 x £18 - £1760 x £ 55 - £1815 per annum for indigenous candidates. Expatriate candidates will be on a consolidated salary of £2060 per annum, and on contract for two tours, the first tour being on probation.

METHOD OF APPLICATION:

Application Forms are obtainable from the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, Apapa Dockyard, and should be completed and returned so as to reach him not later than the 28th of June, 1961. Candidates in the Service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward them to the Personnel Manager along with confidential reports.

---

## ISE KI PANI, AYO NI PA ENIA

Lati Qwo:- SIMEON ADEGOKE FATOKI

O BERE LATI OSU TO KOJA

Nigbati ọkunrin yi ka akọle yi tan o fi ori le ọna ile Ayọ, lasiko yi ni osi awo ile Ayọ lọkankan. B oti Ayọ si ile Ayọ bayi ni ori ti Ayọ jade si ita lati wa pade rẹ, nigbati ori ẹru ba pupọ nitoripe Ayọ dabi Oba osi doju bolẹ nigbati ori Ayọ Ayo sare pade rẹ, nigbati ori ẹruba pupọ nitoripe Ayọ dabi ọba osi daju bole nigbati ori ayọ. Ayo sare pade rọ osi fa dide nile. Ile ayọ dara pupọ ti ofijẹpe golu ni wọn fi ṣe ogiri ati pe gbogbo aga ti owa nibẹ je eyiti wọn fi okuta olowo iyebiye gbe, Ile yi dara pupọ ti ofijẹpe okunrin yi ko le joko si ori awọn aga wonyi. Ṣugbọn nigbati ayọ sọ fun pe ki o joko ni oba si joko Nigbati ojoko tan Ayọ bilere ohun ti owa de ọdọ on. Ọkunrin na si bere si ọrọ isọ oni, "Mo wa ni ile aiye, mo si sisẹ-sise oko ni ohun-kohun. Ṣugbọn nigbati ọdi ọjọ kan mo rosu ninu ara mi pe ki nkuku wa to iku lọ ki osi pa mi. Ṣugbọn si i alẹnu mi nigbati mo de ọdọ iku esọ fun mi pe on ki pa enia ni ipakupa, afi ti mo ba le lọ gba iwe wa lati ọdọ ẹnyin Ayọ. Idi re ni yi ti mo fi de ibi yi." Nigbati ayọ gbọ bayi ẹrin pa, osi sọ fun ọkunrin yi pe lotọ ni on nfun enia ni iwe lọ si ọdọ iku ṣugbọn ki ṣe pe kiakia ni on ma nfun enia ni iwe bẹ. Oni lati tun pada lọ si ile aiye na ki o si jẹ igbadun ti ki awo bi o ṣe wuwa si ọmọ araiye. Nigbati ayọ so bayi tan o wọ inu yara rẹ lati lọ fun ni ẹbun orisirisi. Bi ayọ ti jade, o ko ọpọlọpọ dukia jade pẹlu owo, aṣọ, aya, ọla, kẹ'ẹkẹtẹ ẹsin, ati gbogbo ohun alumoni aiye yi o si ko fun ọkunrin yi o ni ki o ma lọ ni alafia, Nigbati ọkunrin yi ri g b o g b o ohun ti o fun on inu rẹ dun pupọ lati gba awọn ẹbun na o si gba ile aiye lọ.

IYO KU YIO PA RI NI OSE TO MBO

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16 Bamgbose Street, Lagos Phone 21985. Olotu: E. A. Adeniji 51, Tejuoso Street Suru-Lere YABA

FUN OWO IROHIN IMOLE ỌDUN KAN
EKO:- Ṣile merin ati kobo merin (4/4d)
Ilunirah ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile Mefa ati Kobo Mefa (6/6d)

## IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi se ikede fun gbogbo Ọkawe Irohin Imolẹ Jake-Jado Agbaiye ati awọn Ọmọ Karọ-o-jire pe anfẹ:- Eniti o ba le ba wa fi awọn ọrọ si ibiti a fa ila kekere si, ati pe awọn kan tun wa ninu re ti a ko to dada- anfẹ ẹniti o ba le ba wa to si ipo rẹ dara-dara ti yio si ni itumo.

Enikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo rẹ yio gba Ebun ponun-kan sile-kan (£1 : 1/-).

ỌRỌ NA NI WỌNYI

Ọrọ yi jẹ oruko awọn ẹnia pataki nilẹ Yoruba ti nwọn si ti di ologbe:-

1. ... A .. Y ... , 6. M ... E ...
2. O ... N ... 7. ... A ... O.
3. ... U ... W ... 8. O ... O ... I.
4. O ... P ... 9. O ... N—O ...
5. B ... —N. 10. A ... T ...

Orukọ yi jẹ, orukọ awọn Oba nilẹ Yoruba

1. O ... N ...
2. E ... J ... B ...
3. A ... W ...
4. O ... D ...
5. A ... U ...

Tun awọn ọrọ wọnyi to dara-dara:-

1. GOOINANS ...
2. AIJNIDE ...
3. GABRNOI ...
4. ASLIHE ...
5. OINMMION ...

Awọn orukọ wonyi jẹ orukọ Ilu ni ilẹ Naijiria:

1. ... G ... O
2. I ... B ... A ... O
3. K ... A ... C ... N
4. A ... T G U
5. ... A ... B ... K.

AKIYESI:— IDIJE yi yio pari ni gbagba ni ọjọ kẹta oṣu keje ọdun yi (3 : 7 : 61) kọ ọrọ tirẹ ki o han rekete, ẹniti tirẹ ko ba han, a o fa ye ni, ki ẹ si mọ d a j u wipe, ko si ojoro ninu Idije na, ẹniti o ba ṣe gbogbo rẹ, ti o si gba a, ni a o fun ni Ebun ponun-kan Ṣile-kan (£1 : 1/-) Postal order ranṣẹ si.

Fi Stamp Toro ranṣẹ fun gbigbe ponun-kan Ṣile-kan ti o ba jọ ranṣẹ si ọ. Gẹ ibiti Idije yi gbe wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Toro tirẹ. Enikẹni ti ko ba ge Idije tire ranṣẹ, ti ko ba si fi Stamp Toro ranṣẹ pẹlu, ti o ba jẹ a ko ni fi ranṣẹ si onitọhun, a ko si ni fun ni Stamp rẹ pada mọ.

Orukọ ....................

Ibugbe ....................

....................

I-ẹ ....................

Ojo Ori ....................

Fi Idije tire ranṣẹ si:

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS